Bó Ò Ṣe Ní Jẹ́ Kí Eré Ìdárayá Pa Ojúṣe Rẹ Lára

Kí nìdí tó fi dáa kó o kọ́kọ́ ṣe àwọn iṣẹ́ tó yẹ kó o ṣe kó o tó ṣeré ìdárayá?
Ìwé yìí máa jẹ́ kó o mọ ìdáhùn.



ERÉ ÌDÁRAYÁ **OJÚṢE RẸ**

Yẹ̀pẹ̀ yìí ṣàpẹẹrẹ eré ìdárayá. Àwọn òkútà yìí sì ṣàpẹẹrẹ ojúṣe rẹ, ìyẹn àwọn iṣẹ́ tó yẹ kó o ṣe.

Kí ló túmọ̀ sí?

Tó o bá kọ́kọ́ kó àwọn òkúta ńlá sínú ike kan, tó o wá rọ yẹ̀pẹ̀ dí àyè tó ṣẹ́ kù níbẹ̀, ike náà máa gba méjèèjì. Àmọ́ tó o bá kọ́kọ́ rọ yẹ̀pẹ̀ sínú ike náà, kò ní gba gbogbo òkúta yẹn.

www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

Èwo lo máa ń kọ́kọ́ ṣe?

Wo èyí tó ṣàlàyé irú ẹni tó o jẹ́ nínú àwọn àwòrán alápá méjì tó tẹ̀ léra yìí, kó o wá yan A tàbí B nísàlẹ̀ apá kọ̀ọ̀kan.



A

☐ Mo dà bí ẹni tó kọ́kọ́ kó yèpẹ̀ sínú ike.

B

☐ Mo dà bí ẹni tó kọ́kọ́ kó òkúta sínú ike.

www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

Wá ṣe iṣẹ́ yìí:

Kọ àwọn iṣẹ́ tó ẹ̀ẹ́ kó o máa ṣe lọ́ṣọ̀ọ́ṣẹ̀.

Kọ àwọn eré ìdárayá tó o gbádùn jù lọ. Fi àwọn èyí tó o fẹ́ràn láti máa ṣe tàbí wò kún un.

Wá kọ gbogbo ohun tó o ti kọ sí apá méjèèjì yẹn sí ìsàlẹ̀ yìí, kó o bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú àwọn tó o kà sí pàtàkì. Wò ó bóyá "yẹ̀pẹ̀" tàbí "òkúta" ni ọ̀kọ̀ọ̀kan, kó o sì yan èyí tó bá jẹ́.

1		☐	☐
2		☐	☐
3		☐	☐
4		☐	☐
5		☐	☐
6		☐	☐
7		☐	☐
8		☐	☐
9		☐	☐
10		☐	☐

Ṣé ohun tó jẹ́ ojúṣe rẹ làwọn ohun tó o kọ́kọ́ kọ àbí eré ìdárayá? Tó bá jẹ́ pé eré ìdárayá lo fi ṣáájú àwọn ohun tó yẹ kó o ṣe, a jẹ́ pé ó yẹ kó o ṣe àwọn àtúnṣe kan kó o lè rí gbogbo ẹ̀ ṣe.

Tó bá jẹ́ pé ojúṣe rẹ lo fi ṣáájú, wàá lè ṣe àwọn ohun tó ṣe pàtàkì, wàá sì tún ráyè ṣe eré ìdárayá.

"Máa wádií dájú àwọn ohun tí ó ṣe pàtàkì jù."—Fílípì 1:10.

www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania